# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 823 LAGOS SATURDAY JUNE 15 JUNE 21 KỌBỌ MEJI (2) 1963


Olofofo Kan Tu Won Fo:

# Minisita Kan Binu Fise Sile Nitori Pansaga Obinrin

LONDON — Pansaga ọmọge kan ti orukọ rẹ njẹ Christine Keeler ti awọn ọlọpa pe ọjọ ori rẹ ni ọdun mọkọnlelogun ni a gbọ wipe o jẹ ki minisita alamojuto abo ilu Gẹsi, Ọgbẹni John Profumo binu fi ipo iṣẹ ula ze ti o nṣe silẹ laipẹ yi nitori ẹsun kan ti awọn aṣofin ile igbimọ Ijọba ilu Gẹsi na ka a si lorun nipa ọmọge na, nwọn ni awọn fura si Minisita Profumo wipe nkan buruku kan da ton pẹlu pansaga yi pọ; nwọn ni awọn si ro wipe nkan ti o pa awọn mọ eji pọ na le ko nkan ipalara ba gbogbo orilẹ ede awọn.

Wahala ọrọ na bẹrẹ lati nkan bi oṣu mẹta sẹhin ti Minisita yi purọ fun awọn aṣoju ile Igbimọ aṣofin wipe on ko ba ọmọbinrin ọmọge ti nwọn nfọgun on nipa rẹ yi ṣe nkankan pọ rara n gbana; o ni bi on ba gbọ ọrọ na lẹnu enia kan lode ti ko nṣe ninu ile aṣofin yi, on yio pe oluwarẹ lejọ si Kotu pe onitọhun ba on lorukọ jẹ.

Ṣugbọn ni ọsẹ ti o kọja yi ni akara tu sepo, Minisita alamojuto abo ilu Ijọba Gesi na ni ki nwọn ṣe on jẹjẹ, irọ ni on pa, on ti nyan ọmọge Keeler ni ale ti pẹ.

A gbọ irohin wipe gbogbo igbati Minisita yi nlọ pade ọmọbinrin yi ninu ile Dokita Ward ni ikọrọ kan,

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

# Alhaji Adegbenro Pade Agbako Moto

EKO—Alhaji Dauda Soroye Adegbenro, igbakeji baba ẹgbẹ awọn Ọlọpe pade agbako jamba mọto ni alẹ ijeta leti Agege nigbati o mbọ wa si Eko lati ṣe ipade kan pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ; wara were nwọn si ti gbe e lọ si ile alaisan ni Suru-Lere fun itọju.

Oniro'iin Eleti- Ọfẹ ni le ti Oko-Ọba Lẹba Abule Ẹgba ni agbegbe Agege ni mọto-ayọkẹlẹ ti Alhaji Adegbenro na wọ kọlu mọto 'Bọlẹkaja' kan, dẹrẹba awa mọto rẹ pẹlu ibatan rẹ kan, ti nwọn npe ni Taiwo ni nwọn wa ninu mọto na nigbati jamba na ṣẹlẹ.

A gbọ wipe Alhaji Adegbenro fi ori a'i ọwọ rẹ bẹ jingi pupọ sugbọn awọn dokita ti di gbogbo ọgbẹ na fun un. Ibatan rẹ Taiwo fi ara pa pẹlu, a fi dẹrẹba rẹ ni Ọlọrun yọ ti nkankan ko ṣe e.

Awọn ọmọ ẹgbẹ A.G. ti nwọn fẹ ṣe ipade nla kan ni Ikẹnnẹ ni owurọ oni ti sun ọjọ ipade wọn na siwaju si nitori tirẹ.

Pantiwa!

## Awon Minisifa Fowo Kun Owo Omi L'Eko

EKO— Sangba fọ! A gbọ irohin kan loru ana wipe awọn Minisita ilu Eko ti fowo kun owo-omi. Gbogbo awọn ti nwọn ti nsan sile mejo ati kobo mẹrin, a ma san ṣile mẹwa lori pọnun kọkan iye ti ti nwọn ba ṣiro wipe ile wọn na to.

(Wo yoku loju ewe ewe kẹjọ)

## Kennedy Baale Ilu Amerika Pegede

TUSCALOOSA, ALA—Ka ko ti ẹgau kuro ninu ọrọ ti o wa nilẹ, baalẹ Kennedy tiṣe alakoso gbogbo ilu Amẹrika pegede lori ọrọ awọn ọmọ alawọdudu akẹkọ meji ti Gomina ilu Alabama, Ọgbẹni George Wallace sa gbogbo agbara rẹ lati ri wipe nwọn ko gba awọn ọmọ akẹkọ na sinu ilewe-giga ti awọn alawọfunfun ti awọn ọmọ na fẹ lọ ma kọ ẹkọ.

Tẹlẹtẹlẹ nigbati Gomina ilu Alabama ti ngbọ irohin wipe awọn ọmọ akẹkọ alawọdudu fẹ fi orukọ silẹ lati wọ ilewẹ giga na ni Gomina na ti nleri kakiri wipe ko nṣe ni aiye ti on ni awọn alawọdudu yio wọ ilewe na.

Eyi mu ki awọn alakoso ofin ilu Amẹrika gbe ọrọ na lọ si Kotu, adajọ Kotu ti nwọn gbe ọrọ na lọ si paa laṣẹ wipe Gomina na ko gbọdọ di awọn ọmọ alawọdudu kan lọwọ rara

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


LAGOS RACE CLUB

LAST DAY

June Race Meeting

TODAY

First Race at 3.30 p.m.

Admission 3/-

Sweepstakes—Tote, and various other Prizes

# Awon Janduku Amerika Yinbon Pa Alawodudu Kan

JACKSON, MISS. — Okunrin alawodudu kan ti oruko re nje Medgar Evers, en odun metadinlogoji ni a gbo wipe o pade agbako lodo awon janduku Oyinbo ara Amerika kan ti awon fi ibon pa a ni a ja fon nitoripe o je enikan ti o wa ninu awon enia dudu ti nwon so wipe ki nwon ye fi iya je awon nitori awo ara awon.

## Ebun Owo

Irohin ti a gbo nipa Ogbeni ni na ni wipe o je akowe awon egbe enia dudu ti nwon faake kori wipe dandan awon ni lati gbara awon sile lowo awon Oyinbo Amerika ti o gbogun ti awon.

Akowe patiki ni Ologbe na je ninu egbe ra, o si je alakikanju enia. Nwon ni bi o ti ti ipade egbe na de ti o mbo sile ninu moto-ayokele re ni awon janduku na yinbon fun un, o si subu lule, awon aladugbo re si gbe cigba digba lo si ile alaisan, nibe ni o ku si.

Awon omo egbe re ni Ologbe na ti fi igba kan rowe gba lati odo awon enia kan wipe ti ko ba sora re lori oro awon alawodudu egbe re, awon ni awon yio pa ni ipakupa.

A gbo wipe okunrin ti awon pa na ni bi awon ba pa on sori oro awon alawodudu na o te on lorun nitoripe on ko le fi oju on sile ki iya ma je awon enia on rara.

Onirohin wa ni awon omo egbe ologbe na ti fi iwe sode wipe enikeni ti o ba le se ofofo so oruko eniti o pa okunrin na fun awon, awon yio fun oluware ni egbejidinlogun ponun o din ogorun (£3,500) laiboju wehin. Owo olopa ti te ibon ti nwon yin pa okunrin na ni ana.


Hover!

Refuse a trial run before you choose a car. Let the cars speak for themselves and be scrupulously critical when looking at different models. We are convinced (from long experience) that any Mercedes-Benz will pass such an examination with top marks. Please give us the opportunity of substantiating our claim.

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

Lagos . Ibadan . Kano . Kaduna . Jos . P. Harcourt . Aba

Sub - Distributors:

ARMELS TRANSPORT LTD.

Benin City . Onitsha . Aba



HINDU SANKARA'S

Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclosed 4/- money order by air Mail for Catalogues and Literature, HINDU SANKARA 20 Montipelier Row, Blackheath, EO/9 London, S.E.5, England.


# Kele Gbe Awon Baba "Onigbo" Ni Ghana

GHANA—Awon alamojuto Ijoba ilu Ghana ase eto lati fi kele gbe awon baba ti o ngbin ewe taba "igbo" ni ilu Aganyin lowo lowo nisisiyi. Ogbeni Ashford Inkunsah tise Minisita alamojuto eto aralile ni o so oro yi ni Accra lana.

Nwon ni ti ofin ti awon nse paramu re lati gbe jade yi ba jade, o je wipe awon baba agbe ti o ngbin ewe taba oloro na wo gawu.

Minisita na ni enikeni ti Ijoba awon ba mu lori wipe o gbin ewe taba na, ewon gbere ni awon yio fi si titi di ojo iku oluwa re.

Onirohin wa ni on ri eda iwe ofin ti nwon fe se na lori awon ti awon olopa ba gbamu, ti nwon ba nmu ewe taba "IGBO" ewon ogun odun ni awon yio ju won si. Nwon ni awon ko fe ki ewe taba "igbo yi ba awon omo awon je rara.

Awon Iwe Asiko:

# Aggrey Omo Ilu Afrika (1)

## Lati Inuwe ALUFA ATILADE

Laişe iyemeji ọpọlọpọ wa ni a ç iwe igbesi aiye awọn enia olokiki ti nwọn ti lo si aiye, ti nwọn ti hu iwọn iba iwa rere ti nwọn le hu, ti nwọn si ti jade ninu aiye na; sugbọn ọrọ itan igbesiaye awọn enia na, lọkunrin ati lobinrin, a ma fun wa ni işiri ki awa na le ma mọ bi a o ti şe lo igbesi aiye ti wa si.

Laipẹ yi ni a tufọ Alufa-agba ti awọn Ijọ Şọşi Aguda, Eni-Ọwọ Pope John Kẹtalelogun ti o jalaisi ni Rome. Nigbati awọn iya ati baba rẹ bi i saiye nwọn ko mọ wipe o le de ipo olokiki ti gbogbo agbaiye yio ma da orukọ re loni.

Agbẹ-aroko ni baba rẹ on paapa si nran baba rẹ lọwọ ninu oko nigbati o wa lẹmọde. Kişe ọmọ oninakuna, ko si ya ọlẹ enia o si gbọran si awọn iya ati baba rẹ lẹnu.

Itan igbesiaye ti ẹniti a fẹ ki ẹnyin ọkawe wa ka lọsẹ yi ni ti ọkan ninu awọn ọmọ ilu wa kan ti orukọ rẹ njẹ J. K. AGGREY, ọmọ ilu awọn Aganyin ni.

Itan igbesiaye rẹ ti a da nínú iwe AKỌKA YORUBA (apa karun) ti Alufa (Rev.) E.A. ATILADE kọ dun pupọ. Ẹ le ri iwe na ati awọn miran ti o kọ ra lọdọ awọn onişọbu ti o nwọn nta iwe kakiri tabi lọdọ Alufa Atilade alara paapa ni No. 6, Aşabi Street (Ogunmokun Road) Mushin. Ngẹrẹ, tabi ti o ba si ie wipe iwe ni ẹ fẹ kọ lati fi ra iwe na ni, ẹ le fi iwe na sinu apoti iwe bay: P.O Box 263, Ebute-Mẹtta, Nigeria yio si tẹ ẹ lọwọ. O ya, ẹ jẹki a ba itan igbesi aiye Dokita Aggrey lọ gẹgẹbi Alufa Atilade ti on paapa jẹ olukọni pataki ti kọ ọ:—

### Aggrey Ti Afrika

Ọkan ninu awọn ọmọ ibilẹ Africa ti gbogbo enia Dudu ni Afrika ati Amẹrika ati awọn Enia Funfun kakiri aiye feran pupọ ni ọkunrin ẹlẹkọ kan ti a npe ni James Emman Kwegyir Aggrey. Ara ilu Cape-Coast ni Ghana ni Aggrey işe, o si jẹ ẹya awọn Aganyin ti a npe ni Fanti.

Nigbati Aggrey wa ni ọmọde, o lọ si ile ẹkọ ti Methodist Church ti o wa ni ilu rẹ. Lati kekere ni ọmọ yi ti fi eju si ẹkọ rẹ dada, o si jẹ ọkan ninu awọn ọdọmọde ti nwọn tete pari ẹkọ wọn ninu ile iwe na. Lẹhin igbati Aggrey kuro ni ile ẹkọ yi, a ran a lọ se oluko ni ileto kekere kan ni ilu oke.

Aggrey fi tayọtayọ gba işẹ yi, o si şe e tọkantọkan to bẹẹ gẹẹ ti ilọsiwaju pupọ fi wa ni ile ẹkọ na e yi mu ki awọn alaşẹ ti Ijọ Methodist ni Cape Coast gbe Aggrey pada lati şe olori ile ẹkọ nla Ijọ Methodist ni Cape Coast, nigbati on ko iti tu ọmọ ogun ọdun arara.

Lẹhin igbati Aggrey ba ti jade kuro ninu ile ẹkọ tan, on a mu ıa lọ lo akoko rẹ ninu ile işẹ ti o wa ninu ọgba Mission nibiti nwọn gbe nkọ oniruru işẹ bi işẹ gbenagbẹna Işẹ alagbẹdẹ ati awọn oniruru işẹ ọwọ miran. Işẹ ti o wu Aggrey julọ ni işẹ iwe tite. O şe aapọn lati kọ işẹ yi, o si mọ o daadaa.

Ni akoko ti Aggrey nşişẹ ninu ile iwe yi ni ọkunrin oniwasu, enia dudu kan ti ilẹ Amẹrika wa si Ghana. Enia nla ni ọkunrin yi işe, nitoripe on ni Bishop ti Ijọ Methodist ti awọn Enia Dudu ti ngbe Ilẹ Amẹrika.

Ifẹ Aggrey fa pupọ si ọkunrin yi, o si farabalẹ lati gbọ ọrọ rẹ. Lati ẹnu Bishop yi ni Aggrey gbe gbọ irohin nipa orişirişi anfani ti o wa fun ẹkọ giga ni Ilẹ Amẹrika. Aggrey pinnu pe on yio lọ si Ile Amẹrika fun ẹko giga ki on ba le wulo si larin awọn enia rẹ.

Inu Bishop yi dun lati ran ọrẹ rẹ yi lọwọ lati wọ le ẹko ni Amerika. Ẹkọ işẹ iwe titẹ ti Aggrey ti kọ nigbati o nşe işẹ oluko ni ilu rẹ ni Afrika wulo fun u pupọ ni Amerika, nitoripe on le şişẹ ni ile iwe titẹ lati ran ara rẹ lọ si ile ẹkọ. O kọ ẹkọ fun ọpọlọpọ ọdun, o si gba ọpọlọpọ oye ninu iwe mimọ. Nikẹhin, o jade ni Ile Ẹkọ Giga ti Kọlọmbia.

## Adajo Ju Eniti O Pe Oloye Akintola Lole Sewon Ose Meji

IBADAN - Adajọ Kotu awọn ọlọpa kan ti orukọ rẹ njẹ Ọgbẹni Sam. I. Adeşọkan sọ ọdaran kan ọmọ ọdun mọkandinlogun ti o njẹ Rashid Olowu si ẹwọn ọsẹ meji fun ẹsun wipe o bu Oloye S.L. Akintọla ni OLE.

Awọn ọlọpa ti nwọn wọ ọdaran na wa si iwaju adajọ ni, lọ ọ ti nkan yi şele, Oloye Akintọla tişe Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun nbọ lati ode kan ni o ba ọdaran yi pẹlu awọn ẹlẹgbẹrẹ rẹ ni ibi ti a ile ibişẹ awọn Oyinbo onimoto.

Bi nwọn ti ri moto Olotu na ni nwọn bẹrẹsi hu le e; awọn ọlọpa ni ọdaran yi bẹresi lọgun wipe "AKINTỌLA OLE! AKINTỌLA OLE!! Were o si bẹrẹsi sa lọ.

Awọn Ọlọpa ni dẹrẹba anamọto Oloye Akintọla yara da mọto rẹ duro, nwọn ni, ni on na ba bọ silẹ ni o sare tẹle e.

Ọlọpa ti o wa ninu mọto pẹlu Oloye Akintọla lọra sẹrọ ni Kotu pẹlu akọwe Olotu na

Loya Alhaji Obişesan ti ọdaran na gba ni idajọ na ko tẹ awọn lọrun rara, awọn fe gbe e lọ si ibiti bi tiki di a'ẹ.

# Awon Onifayawo Wo Gawu Ni Nigeria

IKẸJA—Ọrọ awọn onişẹ fayawọ ti nwọn nṣiyẹ loju omi larin agbegbe Calabar si Fernando Po, ti nwọn nko ẹru rọbirọbi wọlu fẹ de opin ni isiyi nitoripe awọn ọkọ aropileni ti awọn onibode Ijọba fẹ ma lo lati fi mu wọn ti de si Nigeria.

Ni ijẹjọ ọjọ Ẹti (Satide) ni nwọn sọ ọkan loruko ni Ikeja ninu awọn ọkọ aropileni mẹta ti Ijọba Apapọ şe ra. "RIBADU" orukọ ọkan ninu awọn Minisita wa ni nwọn sọ ọ. Nibi aşeye isọlorukọ yi ni Oloye Okotie-Ebo tişe minisita alanojuto eto inawo Ijọba se ede, ti o sọ fun gbogbo ilu wipe owo iyebiye ni a nşon npadanu lori oja fayawọ ti nwọn nko wọ'lu, ti iwọn ko nsan owo-bode e lori.

### Oko Alami

Oloye Okotie-Ebo ni bi nwọn ti gẹọn nile ọkọ ni awọn nile rẹ; o ni awọn ti ri wipe awọn janduku onifayawọ paapa ni ọkọ ofurufu ti wọn ti nwọn fi nşe alami lati

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

# ELETI—OFE

A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMS

28, Kosọkọ Street, Lagos,   "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467   Phone 23370

VOL XIV. NO. 873 SATURDY JUNE 15 — JUNE 21 1963


## Oro Olotu :

# Obo Ni Yio Pa'ra Re

O jẹ ọrọ-aṣa kan pataki fun awọn Yoruba ti nwọn ba ṣe akiyesi, ti nwọn ri wipe ẹnikan ti o wa ninu ipo eyẹ ati iyi, ti ọla ati agbara wa lọwọ rẹ ṣugbọn ti o nfẹ ṣi agbara na lo, ti o nfẹ fi ayọ fọ ọ; awọn agbalagba Yoruba a ma wa fi ọrọ yi ṣe ikilọ fun bayi: ỌBỌ NI YIO PA ARA RẸ.

Iru ọrọ-ikilọ bayi ni awa oniwe irohin Elete-Ọfẹ fẹ fi ṣe itọka si fun Gomina kan ni ilu Amẹrika ti nwọn npe orukọ ilu ti o wa ni abẹ rẹ ni Alabama, ti orukọ on alara paapa njẹ George Wallace ti o fi aake kọri wipe on ko fẹ ri enia alawọ-dudu kan nibiti awọn Oyinbo alawọ funfun ba gbe wa, yala o ṣe Ṣọṣi ile-ijọsin ni, tabi ninu ile ẹkọ ni, tabi ile ijẹun ni, ti awọn ti o ju u lọ ṣe ikilọ fun un titi wipe awọn ki ṣe aiye bẹ, ti o kọ.

Iru awọn enia bi Gomina ilu Alabama, Ọgbẹni Wallace, pọ pupọ ninu aiye wa nisisiyi, iru awọn enia bẹ si ni a fẹ ki nwọn fi ọrọ asaro kan ti Alufa (Rev.) . A. Atilade kọ sinu iwe rẹ kan ti o pe ni: IWE IKILỌ FUN AWỌN ỌDỌ ti o wi bayi kọgbọn:

### Ma Fi Ida Na Se 'Jamba

1. Ọwọ rẹ jaja tẹ eku ida agbara,
   O bẹrẹ si fi ida na ṣe 'jamba fun ọta rẹ;
   Eku ida na la bọ s'ọwọ ẹlomiran,
   A si wa pada fi ṣa ọ l'ọgbẹ.
2. A jaja gbe ọ si ipo agbara,
   O bẹrẹ si fi ipo na ṣe jamba f'ẹlẹgbẹ rẹ;
   Ida ipo na le bọ sọwọ ẹlomiran,
   A si wa pada fi ṣa ọ l'ọgbẹ.
3. A jaja fun ọ ni ọpa agbara,
   O bẹrẹ si f'ọpa na ṣe'jamba f'ẹnikeji rẹ;
   Ọpa agbara na le bọ sọwọ ẹlomiran,
   A si wa pada fi ṣe ọ l'ọṣẹ.
4. A jaja fun ọ ni gege agbara,
   O si fi gege na ṣe jamba f'aladugbo rẹ;
   Gege agbara na le bọ sọwọ ẹlomiran,
   A si wa pada fi ṣa ọ l'ọgbẹ.
5. A jaja fun ọ ni oruka agbara,
   O bẹrẹ si fi oruka na gba'ju ọta rẹ;
   Oruka agbara yi le bọ sọwọ ẹlomiran,
   A si wa pada fi ṣe ọ l'ọṣẹ.
6. A jaja fun ọ ni fila agbara,
   O si fẹ ma fi fila na ṣe'jamba f'ẹlẹgbẹ rẹ;
   Fila agbara na le bọ sọwọ ẹlomiran,
   A si wa pada fi ṣe ọ l'ọṣẹ.

Ọrọ re o, ẹnyin alagbara aiye, iyoku di ọwọ yin!

# Iwe Si Olotu

## Awon Oyiubo Dun Balo Pupo

Ẹjọwọ, Olotu, mo ṣe bi laipẹ yi ni a nfun ẹ u kiri wipe eyiti a ṣe nipa awọn Oyinbo nwọnyi to, a ko ni gba ki nwọn ma paṣẹ fun wa mọ; awa na ti to oju bọ; a ti to ọdọ re, kinni wa se ti o jẹ wipe a ko le fi OYE wọn ṣere rara?

Bẹni nipa nkan ilọsiwaju ilu; bi a ko ba ti gbe igba bara de ọdọ wọn, nkan ko tu ṣe ẹnu re

Olotu, ẹ jọwọ, o dabi ẹnipe awọn oṣelu wa nilẹ enia dudu lati ma tan wa jẹ. A ti ri ba awọn Oyinbo si lo ti pẹ, ara wọn si gba enia, nwọn ni suru, nwọn si gbọn; ... emi Ọlọrun si wa fun wọn. Bi a ba wa nfẹ ki ilu ki o tutu, ki a fara we wọn.

Emi ni,

Atobajẹ, M. Adewale

Agege

## Idahun Si Ibere Mopelola Amope

Olotu, ẹ jọwọ ẹ gba mi laye lati dahun si ibere Mopelola Amọpe. ọmọ ọba okerimi ti o jade lọjọ Kẹjọ oṣu Kẹfa ọdun ti a wa ninu rẹ yi, ti o sọrọ lori awọn ọmọ mẹta ti ekinni nje Kọla, ekeji nje Kayọde, ẹkẹta a ma jẹ Ọmọtayọ lori iṣẹ ti awọn mẹtẹta se.

Ẹni ti o ṣe iṣẹ julọ ni Ọmọtayọ nitoripe on ni o to egungun ati awọ ara iya won, ṣugbọn ko si ẹmi lara rẹ, nigbati Ọmọtayọ mu ẹmi si lara lo to le sọ rọ. Nigbati a ba to egungun jọ ti awọ ara wa lara, ti ko ba si ẹmi nibẹ yio pada di egungun bi o ti ṣe wa ni, nitorina Ọmọtayọ lo la agbara ju gbogbo wọn lọ.

Olotu, ẹ ṣe pupọ, ọkọ ọba ko ni ṣa yin lẹsẹ atileyin Oluwa a ma wa pẹlu yin.

Emi ni,
Samuel Ogunnuyi Shọrun
(Ọmọ Agba OMU)

# Awon Janduku Gba Lawani Ori Alufa Kolekole Ni Jos

JOS—Awọn janduku enia ti nwọn wa pbọ waasi Alufa kan ti orukọ re nje Malam Sule Ringim, ara Ringim ni agbegbe Kano, ti o nṣe waasi kiri gba lawani ori alufa na, nwọn ni nkan ti o fi nṣe waasi rẹ ko ba ti ode aiye isisiyi mu. Bi ko ba si ti awọn ọlọpa dongari ni, nwọn ko ba tun gba tira Alukurani ọwọ rẹ paapa.

Onirohin wa ni nkan ti o bi awọn ti o fẹ na Alufa na ninu ko ju ti gbogbo nkan ti o ndaruko wipe ko tọ suna ti awọn araiye nṣe nisisiyi lọ. O ni ọna buruku ni gbogbo awọn Alhaji nto lati fi wa owo lọ si Mẹka ati Medina.

O ni Alhaji ti ko ba jeya, ki o fi ẹsẹ rẹ rin, ki o tun gun -akunmi, ko nṣe Alhaji rara. O ni nibo ni nwọn gbe ti ri orukọ mọto ayọkẹlẹ ati Aropilein ninu Alukurani wọn?

O ni inu ina ni gbogbo awọn ti o nfi owo awọn ara ilu ṣe ọla nlọ nitoripe Anabi lodi si iru nkan bẹ.

Awọn Ijọba Ibilẹ Jos ni ti Alufa na ko ba lọ dẹ waasi rẹ na awọn yio wa a kuro ni ilu Jos lọ si Kano.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka Dairo Oloye

Ni ọsẹ ti o koja yi ni mo sọ fun ẹnyin ọkanwe mi wipe aiye wa ti di AIYE-PAJAWIRI sisisiyi. Mo ri a ni OMINIRA PAJAWIRI, Ijọba Pajawiri, Olotu Pajawiri, Adajọ Pajawiri, Gomina Pajawiri, Lọya Pajawiri, Kọtu Pajawiri, Ofin Pajawiri, Ọmọ Ẹgbẹ Pajawiri, baba ẹgbẹ Pajawiri ati nkan bẹẹbẹ ti nwọn nakan Pajawiri.

### Mo Ba E Yo!

Inu mi dun pupọ nigbati mo gbọ irohin pajawiri kan ni ọsẹ ti o kọja wipe A'ayeluwa Ọba ilu Oyinbo fi oye kan da ọmọ ilu wa Olorin ka ti o njẹ Isaiah Kẹhinde Dairo (ọmọ Ijẹsha) lọla, o fun ni oye ti nwọn npe ni M.B.E.

Emi Ayiluka "Eleti-Ọfẹ" ba Kehinde (ọmọ mej) yọ pupọ. Ki nto ma ba ọrọ mi ti ọsẹ yi lọ, o si yẹ ki nki ibeji ọmọ wa na ni iwọnba ranpe. Ọmọ-lẹhinyin o-dagbọn, ara Iṣokun mo ba ẹ yọ o, ṣugbọn boya awọn enia wa diẹ le wa ti nwọn ko mọ itumọ oye MBE ti Ọba ilu Oyinbo fun un yi.

### Awon Aro Oba

Mo ti bẹ Olotu iwe irohin yi ki o jọwọ gba mi laye diẹ ninu iwe rẹ ti ọsẹ yi ki nfi ye awọn ti itumọ oye na ko ye. Ẹ jọwọ ẹnyin ọkawe mi nko tẹ ki ẹ si mi gbọ, nko si fẹ rara ki ikunsinu wa nipa alaye mi ina.

O jẹ aṣa fun Ọba awọn Gẹsi ni ọdọdun ti o ba nṣe ọjọbi rẹ lati ma fi oriṣiriṣi oye da awọn enia ilu ti o ba wa labẹ ọba na lọla.

Ndorina itumọ oye MBE (Member of British Empire) niyi: "eleyi jẹ ẹnikan pataki ninu awọn ARO ti o wa labẹ asia Ọba ilu Gẹsi." Bi emi Ayiluka ti ri itumọ oye pataki ti Ọbabinrin ilu Gẹsi fi Kẹhinde Dairo onilu ere JUJU wa lọla si niyẹn.

### Eru Owa

Mo gbọ wipe awọn eru Ọwa, awọn Ọmọ Ijesha ti nṣe imura lati ba Ọgbẹni Dairo na yọ gidigidi lojo ti yio gba aṣọ oye re. Nwọn ni gbogbo awọn AWE ti o mbẹ nile ati loko ni nwọn a mu eru iṣu kọkan wa sibi aṣeye oye na nitoripe IYAN ni onjẹ awọn Ijẹsha. Enikan sọ fun mi ninu awọn ọlọpanu mi lati Ibadan wipe Gomina Ọlọla Fadahunsi pẹlu iyawo rẹ ti awọn wa ni Ibadan papa yio da ninu ajo-iṣẹ aṣeyẹ yi nitoripe Oloye ARO-AGBA pataki ni Ọlọla Fadahunsi jẹ ninu awọn ARO-ỌBA ilu Gẹsi.

### Oyekanmi

Mo ti mọ Dairo ni Ibadan nigba kan ti mo nṣe akọwe awọn oniṣe irohin kiri lọna Oke Padi mọ Ogunpa ti pe. Bi AWE ba jẹ'yan tan, a fi ẹmu ọguro bẹẹ, ṣugbọn Awe ko tete mọ wipe bayi ni oye gbogbo agbaiye yio yi tete kan on.

Ti a ba ṣe aṣeyẹ oye yi tan mo fẹ ki Awe yi fi ọna han mi nitoripe emi na nfẹ oye ARO pataki fun awọn ọrẹ mi ati fun ara mi. Boya ni Kẹhinde Dairo mọ ọrẹ mi atijọ Tunde King (Baba awọn Oni Juju) ati Ọgbẹni kan ti nwọn npe ni OJOGẸ? Awọn na ṣe bẹẹbẹ nigba aiye tiwọn lori orin-juju nyọ yi.

Mọ niran nkan bi ọdun mokandilogbon sẹhin nigba ogun Itali ati Abisinia ti Tunde King kọ orin juju kan bayi fun wa:

"Itali nleri,
Abisinia nseri,
Ẹ mọ yinbọn
Si Kọlọni wa."

Ki nto pari iregbe mi tọse yi, o yẹ ki nki ara ilu mi, Dokita Moses Adekoye Majekodunmi, Olotu Pajawiri ti Alaiyeluwa Ọba ilu Gẹsi fun ni oye CMG-ọkan ninu awọn ARO pataki fun iṣẹ pataki ti o ṣe larin awọn enia rẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun lakoko Ijọba Pajawiri. "Koye, oye na a mọri.

Abọ mi ni yi o.

# Iyori Ere Bolu Afesegba



Fun bi oṣu mẹfa ni nwọn ti bẹrẹsi ṣe ere bọlu afẹsẹ-gba, ṣugbọn laipẹ yi ni nwọn ṣe ere iyori bọlu na ti nwọn ma ngba lati ka ẹsẹ ere na nilẹ lọdọdun; awọn ọmọ ẹgbẹ meji ti nwọn ba ṣe akinkanju ni nwọn ma nfi agba kan agba. Lọdun yi awọn ọmọ ẹgbẹ ilu Leicester ati ti Manchester United ni nwọn jọ gba bọlu na ni London—awọn ọmọ ẹgbẹ Manchester United lo gba ife Cub ti ọdun yi, aworan wọn niyi nibiti nwọn gbe ti ngba a.

# Idahun Si Ibere Mopelola Amope

## Lati Owo Ezekiel Atoyebi (Omo Sanmora–Igbomina)

Olotu, jọwọ gbami laye lati dahun si ibere omidan Mopelọla Amọpe ọmọ ọba Oke-ri mi tio jade ninu iwe yin oloyinmọmọ ni aipẹ yi, tio bere pe iya kan wa ti o bi ọmọ mẹta ti orukọ ekini nj; Kọla, ekeji njẹ Kayọde ẹkẹta njẹ Ọmọtayọ.

Ti awon mẹtẹta si sọ wi iṣẹ ọwọ ni awọn nfẹ lati ṣe, ti onikaluku si gba ọna tirẹ lọ, ti ọjọ ipade wọn to ti onikaluku si wa fi iṣẹ ti o kọ han nigbati ebi npa awọn mẹtẹta. Eyi ti orukọ rẹ njẹ Kọla fi ọwọ la ilẹ ... si jade, o wa ku ati see bi gbogbo enia ti mọ wipe, ... tutu koṣe jẹ laisi. Eyi ti orukọ rẹ njẹ Kayọde na ... ko ayọ ba wọn, o mu ... na jade lati fi se iṣu na. ... na si jina ni agbara iṣẹ ... t on kọ.

Nigbati wọn jẹ iṣu yi tan ... bi a ti mọ pe bi enia ... jẹun tan omi lamu, eyi ti orukọ rẹ njẹ Ọmọtayọ fi iṣẹ ọwọ ti on na kọ han ... fi fun awọn ẹgbọn rẹ ... omi mu.

Gẹgẹ bi emi ti ri ọrọ na ... eyi bi ko ta si iṣu a ... le fi ina sun ofurufu la- ... ki a mu jẹ, bẹnasini ... kobasi ina iṣu ko le se ... laise. Bakan na sini bi ... ba ri omi iṣu na ko le ... rara ati pe bi a ba ... tan a ko le ṣe alaimu ..., nitori a awọn mẹtẹta ... ni wọn kọ iṣẹ ti o dara, ... mẹtẹta na silọ fi iṣẹ ... wọn na gba arawọ silẹ.

### Ibere Keji

Nigbati nwọn si de ibi Oku iya wọn ti ẹnikan to egungun rẹ mọ arawọn, ti ẹnikan si fi ọwọ ra a ti o si di enia, sugbọn ko le sọrọ rara ki ẹnikẹta to wa sọ ọ iya wọn na di ẹlemi. Iṣe wọn na jẹ iṣẹ iyanu opọlọpọ iṣẹ iyanu na tayọ iṣẹ ọwọ na tun ju ti Dokita lọ gbọ pe onisegun kan fi ẹmi nitoripe a ko si ara enia ri, sugbọn awọn mẹtẹta yi ji, oku iya wọn dide.

Awọn mẹtẹta na si lo ṣe iṣẹ iyanu nitori bi KOLA ko ba ni ero ninu lati to egungun jọ mọ ara wọn KAYỌDE ko ni gbọn ọgbọn ati sọ di enia, beni bi kobasi enia ỌMỌTAYỌ ko ni ri ohun ti yio fi ẹmin si lara, nitorina awọn mẹtẹta ni o ko iṣẹ tio lagbarao, bẹni agbara wọn, to gbẹkẹle lori awọn mẹtẹta ni o lagbara o.

Olotu, abọ mi niyi, mo si dupẹ aye ti ẹ gba mi. Ọkọ ọba ko ni ṣa yin lẹsẹ iwaju ni apọn ebiti nresi, ẹ ko si iwe jẹ o.

# Awon Oni-fayawo

(O berẹ loju ewe kẹta)

fi mọ ibiti ọkọ awọ Ọlọpa ati awọn onibode ba gbe lugo si ki nwọn ba tete sọ fun awọn onifayawọ wipe ki nwọn ṣọra.

Oloye Okotie-Eboh ni ko si ibikibi ti awọn oniṣẹ uruku yi le ba si lori omi nis siyi ti awọn ko ni ri wọn mu nitoripe jomi-joke lokan ninu awọn ọkọ Ofurufu mẹta ti awọn ṣẹṣẹ ra na. O ni bi ọkọ yi ba nsare loju omi ti lati wa awọn onifayawo ọ ti o ba tun wu wọn nwọn a tun tẹ ẹrọ kan lara rẹ, a gbera, o da oke lẹiyẹ nfọhun.

Akọwe onirohin Eleti—Ọfẹ ni on gbọ wipe iru ọkọ jomi-joke yi ni awọn onifayawọ ko fẹ rara nitoripe bi awọn Ọlọpa ati awọn onibode ti o wa ninu ọkọ na ba ko firi wipe awọn kan nko ẹru rọbi rọbi bọ, nwọn si wa ni bi iru Olokemeji s'Eko, ni arin ogun iṣẹju ni nwọn yio ti fo kan wọn lara.

Ṣe ẹnyin na wa ri wipe awọn oniṣẹ fayawọ wọ gawu nisisiyi tabi nwọn ko wọ gawu ?



# Baba Aladie

Gbogbo enia lo nwa ilọsiwaju fun ilu wọn ni Tanganyika, ni ila Orun Afirika ni awọn alamojuto Ijọba ibe ti bẹrẹsi ran awọn ọmọ ibilẹ ilu na lọ si ilu Oyinbo lati lọ kọ orişirişi iṣẹ fun anfani ilu wọn. Aworan ti ẹ nwọ yi ni ni Ọgbẹni Simon J. Ikolo ara Ndala Tabara ni Tanganyika ti o wa si ilu Oyinbo wa kọ iṣẹ a-nsin-adiẹ ni oko kan ni Shroshire Agbebọ Adiẹ kan ti o ṣẹṣẹ ... ẹyin ni o nyẹwo ìọwọ rẹ.

### Igbobi Matron Studies

# London Hospital Administration

LONDON–The Matron of the Royal Orthopaedic Hospital, Igbobi, is the only woman on a hospital administration course with 25 men, organised by King Edward's Hospital Fund for London, and now taking place in London.

One consolation for the Matron, Mrs. Ada Okoro, she is not the only Nigerian on the course. Among the hospital administrators from many parts of the world, is Mr R. A. Ajayi, a member of the internal audit section, Federal Ministry of Health. Both Mrs. Okoro and Mr. Ajayi are in Britain under Nigeria/U.K. technical assitance arrangements.

The course which lasts until 19th July, includes lectures from British hospital management experts, a comprehensive series of visits to the major teaching hospitals in the London area and attachments to these and regional hospital boards. Mr Ajayi told our correspondent yesterday: I have found the attachments to London hospitals so useful that I have made a request to my Ministry in Lagos for an extension of my visit here in order to study the working of the system used in their out-patients department. It was extremely well-organised and from the moment a patient arrived I don't think five minutes elapsed before he was attended to."

Mr Ajayi would also like to study the supplies department of one big teaching hospitals in London.

## Ghanaians At British Engineering Works

LONDON Three Ghanaian technical teachers are studying machine tool practice for six months at the Colchester Lathe Company in Essex, England under Ghana/UK technical assistance arrangements. They are Mr. Paul Adu - Tum and Mr Vicent A.K. Nunekpeku both from Kpandu Technical Institute and Mr. Godson K. Amekuedi from the Tarkwa School of Mines.

All three are spending a number of weeks in every department of the works, learning the techniques of using modern stools from senior craftsmen with many years teaching experience.

## Transistor Radios For Kenya Schoolchildren

LONDON — Over 1,100 transistor radios have been distributed to African primary schoolchildren throughout Kenya to enable them to hear lessons broadcast daily by the Kenya Broadcasting Coporation. The service has been made possible by a grant of £26,300 from the Colonial Development and Welafre fund.

## President of India Arrived in Britain

LONDON–President Radhakrishnan of India arrived in London on Wednesday at the start of an offiial 11-day Commonwealth visit to Britain.

Later the Queen conferred on him the Order of Merit, one of Britain's most distinguished orders of chivalry.

After luncheon at Buckingham Palace, the President drove with members of his suite to Westminster Abbey, where he laid a wreath of orange, green and white flowers on the tomb of the Unknown Warrior.

# Campaign To Raise Money To Relieve Hunger

LONDON—Students from different parts of the world examine fishing nets at a Freedom from Hunger exhibition opened in Leeds, northern England, where the public intends to raise £150,000. With the Lord Mayor, Alderman Harold Watson (centre), and the Lady Mayoress, are Mr. Gottfried Martin Sampong (left), from Juso, Ghana, and Mr. Joseph Sem Anarfi (Second from left) from Ashanti, Ghana, who are both studying accountancy at Leeds College of Commerce

Third from the right is Mr. Durga Singh Patel, of P. O Malawan, District Patna, Bihar, India, who is studying management at the College of Commerce. On the extreme right is Miss Baysan Birgol, from Ankara, Turkey, who is studying in the Department of Nutrition at Queen Elizabeth College, London University.



## Minisita Kan Binu Fise Sile Nitori Pansaga Obinrin

(o bere lati oju ewe kinni)

Ogbeni ara Russia kan Captain Eugene Ivanov, ti awon Gesi fura si wipe ise a ami ni o nse kiri ase wole-wode obinrin pansa ga na pelu.

Awon onilu ni awon fura si wipe gbogbo aşiri ilu nipa gbogbo ibiti awon gbe ba ■ ■ omoge yi a ti mo, ti a si ti gbe so fun ale re ara ilu Russia yi.

Oro na ti fe bige badubi larin awon igbimo aşofin ilu Cyinbo; awon omo egbe alatako (Labour Party) ti ilu Gesi ti faake kori wipe awon ni lati feau kan oro na ninu ile Igbimo ni, awon si fe ki Ogbeni Harold Macmillan, işe Olotu Ijoba Gesi ■ işe si e pelu awon emewa re.

## Kennedy Baale Ilu Amerika Pegede

(o bere lati oju ewa kinni)

lati foruko sile lati wo ile-iwe giga ilu na.

### Gomina Leri

Awon olopa ilu Amerika fun Gomina na ni iwe-aşe ti adajo n a pa, şugbon o ni t i r e ni o so yeu; o ni ti o ba di ejo na ki awon ara ilu o n m a wo nkan ti on a şe; nwon ni ti gomina yi ba rufin adajo na nwon le ju u sewon odun mewa pelu işe aşekara.

Nitoto ni ijeta ti awon omo enia d u d u meji na James Hood a t i Omoge Vivian Malone fe wo ile-we giga n a, Gomina y i lo duro s'enu ona o ni "ko saiye". Boya o nse eleyi ki awon ara i l u re le bi tun dibo fun un wole ni, şugbon nigbati gomina yi ri awon soja omogun ti Baale Kennedy fi ranşe s ilewe na pe bi o ba ti gba n i ki awon şe e, gomina na fehin sile o salo patapata.

Bi o ti nsalo ni o beresi fonnu wipe "ija na şeşe bere ni o, on a ri wipe nwon yo awon omo na ninu ilewe patapata.

Baale Kennedy ni laipe yi on a ri wipe awon iko ile igbimo aşofin fowo siwe ofin ti nwon fe gbe jade lati dero inunibini ti awon Oyinbo Amerika nse si awon alawodudu. Baale na ni nigbati nwon gbe wahala o g u n ti a w o n, awon e n i a d u d u yi ni awon kesi, n w o n si da awon lohun logan nitorina ese ni bi awon alawo funfun ba wa beresi şe ikorira si awon enia-dudu yi.

# Akiyesi

E wo oju ewe keji fun i r o h i n Awon Janduku Amerika ti o yinbon pa Alawodudu kan lori oro inunibini ti nwon nse si won.

# Eleti—Ofe D'araba

# Akorinta Kan W'ewon Nitori Aunti "Koforun"

LONDON—Bi oro aunti "Koforun" omoge eleyinju ege ti nwon npe ni Christine Keeler ti ko ba awon agbalagba ti o ni oruko larin ilu beni o tun ko janni janni ba okunriu akorinta kan ti nwon npe ni ■ Aloysius Gordon ti awon olopa ni o fi igba kan ba omoge na şe ale po şugbon o gbindanwo lati fi ibon pa.

Ni ijeta ni adajo kotu Olola Ernest Roberts, ilu oyinbo ni Old Bailey ju akorinta na sewon odun meta gbako; awon juri ti o joko jiroro lori oro odaran na ni o jebi wipe o fe ba omoge "KOFORUN" na lawo je.

Bayi ni ejo esun ti awon olopa ba odaran na ro niwaju adajo yi, nwon ni lojo ti nkan y i sele, odaran yi lo ba omoge yi ninu ile okunrin kan' Bi o t i fe bo sode lati inu iyara beni odaran na ba yo ibon, bi o ti ni ki on yin in ni awon olopa ba gba a mu, ni nwon gba ibon na lowo re.

O to oşu meta ti awon Olopa fi nwa omoge "Koforun" kiri yi nigbati nwon fe beresi ro ejo na. Awon kan ni o ni lati je wipe awon enia pataki kan ti o mba omoge na lo ni nwon so wipe ki o fara şoko nitoripe awon ko fe ariwo ti oro omoge na fe da sile.

Nitoto opolopo nkan ni ejo omoge na hu sile nitoripe awon olopa ti lo mu Dokita S. Ward, ile eniti nwon so wipe nwon ti mba omoge na lo po. Awon Olopa ti wo dokita na lo siwaju adajo. Ninu esun ti nwon ka si lese, nwon ni awon pansaga ni o fi npa owo.

Nwon ti ni ki dokita na wa enikan duro fun un ni ijeta, nwon si fi ejo igbejo re na si igbamiran.

# Awon Minisifa Fowo Kun Owo Omi L'Eko

(O bere loju ewe kinni)

A gbo wipe gbese iwe omi na a bere lati oşu April ti o koja yi, iyen ni wipe gbogbo awon ti o ye ki nwon ni lati san, awon akowe ibi işe awon munisifa a ma ko mo iwe ti nwon ti ti re jade fun gbogbo enia.

A tun gbo wipe awon Miuisifa Eko nle fi owo kun owo POO ti nwon ngbe kiri n i awon ilu. Iye ti nwon yio fi kun owo POO na, ni a ko ti mo.

A won ile kan ■ ti awon minisifa ni ki nwon ma gba epinni owo-omi lori won, awon ile ■ ni Şoşi ti nwon ba gbe ■ n Olorun, Mosalaşi, ile ijoba, ile-oku, papa ti nwon ba nşere. Nwon ni ■ le san owo omi ■ ■ ■ emeji lodun.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos, Box 467
Phone 23370; Editor: (Olotu) Ola Onatade, 15 Kosoko Street, Lagos.